# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LA WA

No. 579 TUESDAY APRIL, 14 1964 (2D)


## Ẹgbẹ Afẹnifẹre Gba Gbogbo Bọọsi Ilu Eko

EKO:-Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni irohin de si etigbọ wa wipe ẹgbẹ Afẹnifẹre (A. G) ti o wa lori aga ijoko Ijọba Ibilẹ Eko ti gba gbogbo awọn bọọsi ti Ijọba Ibilẹ Eko nlo, awọn o si ma a ṣe alakoso ati Oludari gbogbo awọn Oṣiṣẹ bọọsi na lati oni yi lọ.

Oniwe irohin wa Ejon'gboro fi ye wa wipe Alhaji Musa Yar'Adua, Minista Alamojuto eto Igboro Eko ti fi ọwọ si iwe aṣẹ na pe, ki ẹgbẹ Afẹnifẹre ki o ma a ṣe Oludari eto iṣẹ Bọọsi Ijọba Ibilẹ Eko.

Lẹhin ti Minista na ti fi ọwọ si iwe aṣẹ na tan, ni awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre wa lọ ṣe ipade kekere kan. Ninu ipade na gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni awọn panupo yan Oloye J. A. Ọdẹku ni Alaga Oludari iṣẹ Bọọsi ilu Eko.

Lẹhin na, ni nwọn tun wa yan Igbimọ kan ti yio ma ṣe iranlọwọ fun Ọdẹku ninu Iṣẹ rẹ. Awọn enia ti o wa ninu Igbimọ na ni, T. B. Lawal, R. A Williams, ati Ọgbẹni Benedict.

Awa Oniwe Irohin *Imọlẹ* ki ẹgbẹ Afẹnifẹre ku iṣẹ, a si ki Ọgbẹni Ọdẹku ku Oriire, Ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹṣẹ o.

# AGBẸJỌRO AWOLỌWỌ KỌLU AKINTỌLA

EKO:— Gbogbo enia ti o wa ninu Ile ẹjọ ti o gajulọ fun Orilẹ-ede Naijiria ni nwọn ya ẹnu ṣilẹ ti nwọn ko le pade mọ nigbati Oloye Amofin Ọgbẹni Victor Durand ti iṣe Agbẹjọro Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre kọlu Oloye S. L Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Dẹmọ ninu Ile ẹjọ na ni owurọ ana.



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ**

Ọgbẹni Durand ṣi ọrọ rẹ ti ana niwaju awọn Adajọ Agba marun, Ọlọla Adetokunbọ Ademọla Olori gbogbo awọn Adajọ Agba fun Orilẹ-ede Naijiria, Ọlọla Conrad Taylor, Ọlọla Louis Mbanefo, Ọlọla Lionel Brett ati Vahe Baisamian.

Ninu ọrọ rẹ, Ọgbẹni Durand ṣe alaye fun Ile ẹjọ na pe Oloye S. L. Akintọla ko si ninu ẹgbẹ Ọlọgbọn Ori, eyi ti o ṣe ipade ni Ikẹja ninu ọdun 1962.

Bakanna o tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, nitootọ, on ti mu ẹsun kan an ni ọsẹ ti o kọja ṣugbọn on yio tun ta ni Ọlọbọ ni Owurọ yi.

O ni ẹri ti Dọkita Sanya Ọnabamiro jẹ niwaju adajọ Ile ẹjọ giga Eko ki iṣe ẹri Otitọ, gbogbo awọn ti nwọn si ni Oju-inu ti nwọn si le ronu jinlẹ ni yio gba pẹlu pe, Dọkita Ọnabamiro ki iṣe ẹlẹri otitọ

O ni on fẹ ki gbogbo ile ki o ba on wo o, nigbati nkan ko soju enia, bawo ni Oluware se le mọ ohun ti o ṣẹlẹ nigbati ki iṣe ajẹ ?

O tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, ọrọ agbọsọ ni ọrọ na, o si wa ya ẹnikẹni lẹnu pe lori ọrọ agbọsọ yi ni adajọ fi ṣe atẹgun.

Ọgbẹni Durand sọ ninu ọrọ rẹ pe, 'Adajọ ṣi ararẹ lọna." nigbati o sọ wipe Oloye Awolọwọ fẹ gbe ogun ti Ọbabinrin Gẹẹsi, o si tun fẹ doju Apapọ Ijọba bolẹ.

O ni ọrọ ti Oloye Awolọwọ sọ ninu ọdun 1955, ọdun keje ṣẹhin ni adajọ nsọ, O wa bere pe, "Bawo ni ọrọ ọdun 1955 ti ṣe de ọdun 1963?" kini ọrọ na si ni iṣe pẹlu idoju Ijọba bolẹ?".

Nigbati o sọ ọrọ yi, nṣe ni adajọ Agba mi ori, ti o si fi eti ko Ọlọla Taylor ni eti, awọn marun si sọrọ kẹlẹkẹlẹ fun bi iṣẹju die, ni nwọn ba kọ nkan silẹ ninu iwe wọn, nwọn si kesi agbẹjọro rẹ pe ki o ma a ba ẹ ọ rẹ lọ.

Ki o to bẹrẹsi maa ba ẹjọ rẹ lọ, o sọ fun awọn adajọ pe, ki nwọn fa igi si idi ọrọ na ninu iwe ọwọ wọn nitoripe ọrọ tun mbọ wa kan niwaju.

ISỌKUSỌ

Ọgbẹni Durand tun ṣe alaye pe, ninu ipade ti ẹgbẹ Afẹnifẹre se ni Ikẹja, ohun ti nwọn sọ ninu ipade na ni wipe, nwọn fẹ lọ polowo ibo ni Ipinlẹ Ila Orun, ati Ipinlẹ Ariwa. Ohun meji pataki ni o mu wọn ṣe ipinnu na.

Ekini ni lati le jẹki ẹgbẹ Afẹnifẹre o le di ẹgbẹ ti gbogbo enia mọ ni orilẹ ede yi, ati ekeji ni lati ma gba ẹgbẹ Olomi laye lati le wa jẹ gaba le awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lori.

O tun ṣe alaye pe ti Adajọ ba ka iwe Irohin "London Times" ni Owurọ Oni (ana) yio ri bi awọn enia ti nmura silẹ fun ibo ti mbọ yi, ti ẹgbẹ kan nlọ lati ilu kan de ilu keji.

O tun wa ṣe alaye pe nigbati abayọri ibo na jade, ti ẹgbẹ Afẹnifẹre kuna, Oloye Awolọwọ pe gbogbo awọn Ọ nọ ẹgbẹ rẹ ti nwọn dibo fun ṣugbọn ti nwọn kuna ninu ibo na pe ki nwọn o maṣe bi Ọkan je, ẹgbẹ Afẹnifẹre ni yio di Alakoso Apapọ Ijọba ninu Ọdun 1965.

Nigbati Adajọ Agba Ọgbẹni Taylor bere Ọrọ kan ti Oloye Awolọwọ sọ nigbana Ọgbẹni Durand sọ pe, Dokita Akinọla Maja ti iṣe Baba ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ọrọ na mba wi.

O wa ṣe alaye pe ki adajọ farabalẹ, on mbọ wa ba Ọrọ na niwaju, oni bi adajọ ba si fẹ ki on sọrọ lori rẹ nisisiyi, on ko le pasẹ, eyiti nwọn ba wi ni on yio, ṣe ṣugbọn adajọ ni ki o ma a ba Ọrọ rẹ lọ.

O tun ṣe alaye pe, ohun ti ẹgbẹ Afẹnifẹre da Igbimọ ọlọgbọn ori silẹ fun ni lati ma fun Igbimọ Alabẹṣekele ẹgbẹ na ni imọran ohun ti nwọn o ma a ṣe, ki iṣe pe Igbimọ na npaṣẹ fun ẹgbẹ, eyi ki iṣe ete ẹgbẹ na.

Ọgbẹni Durand mu idiku ninu apo rẹ, o si gbe oju soke, ki o to fi idiku na nu imu tan, ni o ba koju si Agbẹjọro Ijọba ti o si sọ fun ile ẹjọ pe, "Abanirojọ ti ṣi adajọ lọna nipa ọna ti o gba pe awọn enia ti o wa si ile ẹjọ lati wa sọrọ."

Gẹgẹbi alaye rẹ, eyi ti o tun fi han awọn adajọ lati inu iwe ofin, o sọ fun ile ẹjọ pe, Dokita Ọladipọ Maja ni o yẹ ki o kọkọ ro ẹjọ.

Lẹhinna ni o wa fi abọ si ori ẹjọ ti Olesari ati Anthony Eboh, o ni ọna ti abanirojọ gba nipa eto na lodi si Ofin, O si ṣe alaye pe, Ofin ko gba wọn laye lati sọrọ bi nwọn ti ṣe rojọ niwaju adajọ.

Ki o to pari ọrọ rẹ, ni o ti sare ṣi iwe ofin ti o si ka bi awọn enia na ti ṣe le jẹri.

WO OJU EWE KẸFA

# AKINTỌLA RONU

LATI ỌWỌ ABALIFA

OLOTU, bi a ko ba sọ si ọrọ yi, ika ni aiye a pe ni; nitori ina ajo, ile nwo omi ntan lẹhin ẹja. Aanu ṣe ni pe, awọn sọ fun ni pe, awọn ṣofin ni Ibadan pe ki Ogunde ma ṣe ere mọ. Şugbọn inu wa dun pe, nipa ṣişe bayi Akintọla fihan gbangba pe, gbogbo ohun ti o wa ninu ere Ogunde otitọ ni ati pe nipa şişe bayi o fi han pe on ko fẹ ki Yoruba ronu.



OLOYE AWOLỌWỌ

Akintọla ko le fẹ ki Yoruba ronu nitori bi Yoruba ba ronu, baba Dele yio tẹ ni ilẹ Yoruba. Nitori bi Yoruba ba ronu ao ranti pe Akintọla lo da rudurudu silẹ ni Iwọ-Orun ni 1962, bi Yoruba ba ronu ao ranti pe nipasẹ rudurudu yi ni Awolọwọ ati Enahoro ṣe de ẹwọn, bi Yoruba ba ronu ao ranti pe ninu ẹwọn yi ni Awolọwọ wa ti ọmọ rẹ akọbi ti ku iku oro, ti Akintọla ko si pada lẹhin rẹ ti o tun nsọ u lori redio lẹhin ti o mọ pe Awolọwọ ko le sọrọ lati dahun tabi ati ja on bi o ba purọ.



Aworan yi ni ti Oloye Akintola ati omo rẹ 'Dele

Sibẹsibẹ Akintọla ni nitori irẹpọ gbogbo Yoruba ni ohun ṣe nṣe gbogbo ohun ti on nṣe.

O ni iya njẹ Yoruba ati pe Awolọwọ lo nfi wa jiya ko purọ bẹni ko si sọ otitọ ko purọ nitoripe lootọ iya njẹ wa.

Şugbọn ko sọ otitọ nitoripe ko sọ si eti gbogbo enia pe ni akoko ti on nbọ sibẹ ni owo lọ nilu. ni iṣẹ tan, ni airoju de, ni awọn ti ntele lẹhin yọ ada lọ si Ilaro ni akoko ikania. Nisisiyi Akintọla nṣe ara rẹ bi Olufẹ Yoruba.

O nsọkun eke o ni iya njẹ Ọmọ ilẹ baba on. Şugbọn nibo ni Akintọla wa tẹlẹ? ṣebi on na ti wa ṣe Olotu Ijọba gbogbo Eko ri? Kini o ṣe? Şugbọn nisisiyi nitoripe Ibo degbẹ pọ mọ Ẹgbẹ AG, o nwa ohun ti yio fi bi Ibo ninu ki nwọn ma a lọ, nitoripe Ibo njijakadi ki nwọn fi Awolọwọ silẹ, inu nbi Akintọla. Kilo ha ku ti ẹ tun fẹ ṣe!

Bẹ iya ni Akintọla fẹ fi jẹ wa bi o ba mu oke. Ohun to ni on nfẹ ni pe ki gbogbo wa ni ẹgbẹ kanṣoṣo.

Ewu nla ni eyi. Bi aba ni ẹgbẹ kanṣoṣo, ẹnikẹni kole tako ẹgbẹ, bi Akintọla g ẹ g ẹ b i olori ba si ni ki nwọn ju Ọba Ilaro sẹwọn laiyelaiye ki on to sọ ohun to ṣe ẹnikan, ko gbọdọ yii lohun pada Ọgbọn ti awọn ara ilu okere ti ntẹ awọn Ọmọ ilu mọlẹ ṣe ilu ni yi Bi a ba si gba, laisianiani iya na yio ju ti akoko ti a wa labẹ Oyinbo lọ.

Nkan keji nko ro pe Akintọla le sọ pe on ko ni awọn Baba isalẹ kan ti kii ṣe Ọmọ Yoruba. Bi o ba ṣe otitọ ṣe aye ti Oyinbo kuro gẹgẹbi Olori wa ni o fẹ fi awọn wọnni si? A ki i sẹ Ọmọde mọ Ẹnikan ko si le maa pe ole ja, pe Olohun ko ṣọ ohun nitori ati maa jẹ ẹni rere. Oye ki gbogbo Ọba mọ ara wọn lẹni ọwọ Ori ade sa ti di bọọlu ni Iwọ-Orun ibi ba wun oṣelu lo ngba wọn si.

Akintọla npe awọn Ọba jẹri lori redio sugbọn o mọ pe ko si Ọba kan ti o le sọ pe o purọ.

Loni Fani-Kayọde ati Akintọla dọrẹ, ṣugbọn ọrẹ aja ati ẹkun ni, ohun to da wọn pọ ni yio tu wọn ka, o daju, Ohun ti o ndun awa nipe nipa bayi airoju airaye ko ni lopin nilẹ wa, iya yio ma a gori iya. Boya bi Akintọla ba ronu bi ko tilẹ lẹ ki Yoruba ronu boya iya a ye wa a jẹ, boya bi baba Dele ba ro ti awọn alaini ni ilu, a tẹrikodo, boya bi Akintọla ba ro tiwa, a ronu piwada, a ye da ilu ru.



OLOYE ENAHORO



Hubert Ogunde Ati Awọn Elere Rẹ

AT LAST THE WATCH WITH A PERSONAL TOUCH WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

A fortnight after receipt of your photo we will send you a Windsor watch with lifetime guarantee

RÉF. N° 55. PHOTO

Free illustrated catalogue on demand



A Wonderful 15 Jewel lever shock protected movement, non-magnetic, unbreakable mainspring ROLLED GOLD waterproof case and stainless steel back with your name engraved.

Beautiful diamond polish raised figures, luminous and YOUR PHOTO reproduced IN COLOR on metal dial.

PRICE £ 5.

HURRY SEND YOUR PHOTO (any size) with cash or cheque.

WINDSOR

19, Avenue de Lérins - Cannes, France

# Ẹ Ma a Gbadura Fun Awọn Ọmọ Nyin

Ẹ jẹ ki a ma a ronu, nigbogbo igba. Ẹ jẹ ki a ma a ko ijanu ahọn wa, nigbogbo igba. Ohun ti a ba nfẹ fun ara wa, ni ki a ma a fẹ fun ọmọlakeji wa. Ẹ ma ṣe jẹ ki a sọrọ odi si ọrẹ wa, si aya tabi anyanfẹ wa si aladugbo wa, si enikẹni. Paspa, si awọn ọmọ wa. Ọrọ ire ni ki a ma sọ si ara wa ni igbagbo bo fun anfani ara wa. Isọkusọ ko yẹ ọmọ enia. Eni ti ibi rẹ pe, ko ni fẹ lati sọ isọkusọ. Ẹniti ori rẹ pe, ko ni fẹ lati sọ isọkusọ Ọlọrun ko fẹ ki a ma sọ isọkusọ. Ijọba ko fẹ ki a ma a sọ isọkusọ bi eja inu odo.

O ṣe ni, a lanu lati ri i pe awọn abiyamọ miran, lọkunrin ati lobinrin ninu awọn ẹlesin ọmọ iya mi (muslims) fẹran lati ma a bu awọn ọmọ wọn ti o ba ṣẹ wọn. Nwọn yio bu wọn pe, ẹ o ri ori rapata-rapata ẹ o ri eti rẹ bi eti choro ati bẹbẹẹl o Aṣakasa ni eyi jẹ. Nwọn si nkọ ọmọ wọn ni ẹekẹ eebu niyẹn. Ẹko ire ni o tọ, ni o si yẹ ki a ma a fi kọ awọn ọmọ wa.

Awọn obi miran a si ma a fi ibinu sọ fun ọmọ wọn ti o ba ṣẹ wọn pe, "Ori ẹ fọ ni?" "Ori ẹ ba ẹ ni?" "Aṣu nu ni ẹ ni?" ati bẹbẹlọ Aṣa yi ko dara rara. Ẹni ti o ba nsọ irufẹ ọrọ yi si ọmọ rẹ, o nwa iṣubu ati ibi fun ọmọ rẹ na. Ẹ jẹ ki ama a gbadura fun awọn ọmọ wa o ni gbogbo igba. Nipa bayi, bẹ Ọlọrun nigbagbogbo awọn ọmọ nyin yio si di fun iranlọwọ Rẹ. ọmọ ire Ẹ jẹ ki a ma a

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan. 20 - Feb. 18) Ala ohun kan ti o ti nla, yio'ṣẹ laipẹyi, maṣe jafara bi nkan na ba ti te ọ lọwọ yara bẹresi lo o nkan na dara ni lilo fun iṣẹ rẹ.

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Maṣe se iyemeji, ohun kan ti o ngbero lọwọ-lọwọ dara pupọ, bi o ba si ṣe aye wo nipa rẹ, eyi yio jẹ iranlọwọ fun ọ pupọ. Ṣugbọn maṣe jafara si iṣẹ re.

ARIES (Mar 21 - April 19) Alafia yio to ọ loni, ṣugbọn maṣe ṣiṣẹ aṣe yoke, tabi aṣe laagun, akoko na dara lati ṣere pọ pẹlu obinrin tabi ọrẹ. Maṣe binu si ẹnikẹni.

TAURUS (Apl 20 - May 20) Ọjọ oni dara fun gbo gbo nkan, ire airotẹlẹ kan yio yọ si o lojiji, yio si mu inu rẹ dun pupọ ojọ oni dara lati ra oja tabi lati ta ọja tabi lati kọwe.

GEMINI (May 21 - June 21) Alaimọ eto ni tito yio ṣe ifasẹhin fun ọ tobẹ ti iwọ ko fi ni mọ ibiti o tọ lati bẹrẹ, o si le ṣe aṣemaṣe, ki o lọ fori gbari alagbara tobẹ ti iwọ yio fi tun gbogbo eto na ṣe.

CANCER (June 22 - July 22) Oni dara fun ọ nibi gbogbo fun obinrin ati fun ojulumọ. Iṣẹ rẹ yio si ma gberu si lati ilẹ okere wa, ere pupọ yio si wa fun ọ ni jijẹ.

LEO (July 21-Aug. 22) Bi a ba yọwọ ti idalọ wọkọ diẹ to wa kuro, gbogbo ilọsiwaju rẹ yio jẹ rere, edekoyede kan ti o ti wa nile fun ojọ pipe yio pari. Iwọ yio si ri iṣẹ titun gba.

VIRGO (Aug. 23-Sept. 22) Ami di kekere kan yio ba ọ ja, maṣe ṣiṣẹ aṣekara loni. Igba rere yio si silẹ fun ọ nipa ti obinrin.

LIBRA (Sept, 23-Oct. 23-) Ire mbọ wa ba ọ laiṣe ete lẹṣẹ. Arisiki ojiji yio yọ si ọ, iwọ yio si ba gbajumọ ṣọrẹ, maṣe ba wọn ja.

SCOPIO (Oct 24-Nov. 22) Ohun ti o ngbero yio yọri si rere, maṣe jẹki ọrọ ti ko to ọrọ bi ọ ninu, suru ni ki o inu, ọrẹ ni ki o ma ba awọn ọrẹ ati ojulumọ re ṣe.

SAGITTARIUS (Nov. 23-Dec. 21) Mura lati pari ija nla kan, eṣọ di owo re, fetsile si ojo ti nson oro fun o. Owo yio te ọ lowo loni ti o ti wa ko kere to,

CAPRICORN (Dec 22 - 19) Alairi owo na yio wahala rẹ diẹ loni, ṣugbọn iwọ yio ṣe orire nipa ti obinrin.


# EGBOGI JẸDIJEDI

FUN EGBOGI



## "CYCLOVE"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jedijedi rẹ gbe wa lara idi si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho rẹ enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jedijedi jẹ ọkan ninu amod ti o buru ni pataki fun Okunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma powo wọn fun iwosan re ṣugbọn boya ladi mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi won ba lọ si Ile Dokita lati le ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa be awon o bo low re patapata.

Ṣugbọn awa so pe ... Lehin ... diẹ iwonu rẹ yio si tun bere bakana. Oriṣiriṣi Jedijedi ni o wa ekini ti o bere nipa aiko ma ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ọjukaena ṣelu lojojumọ tabi gigun keke ologere (Basikulu, pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi ... ohun adidun popoju nigbakugba. Jedijedi oriṣiriṣi ni o wa, ewo ni tire? Bi o nyọ jade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lehin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti ntin ... ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "CYCLOVE" ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣe wa idi rẹ a ki o si danwo orisi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijedi na pata alafia yio de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogid taa-a gboro ilu Naijiria jakejado, Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)



# Gbanjo o !

Eyi ni lati kedefun gbogbo awn ONIBARA wakọ jake jado agbaiye pe ao bẹresi ma a ta Oja gbanjo wa fun ti Ọdun EASTER ati ILEYA gẹgẹbi iṣe wa lọdọọdun Ohun ti o tun mu wa tete bẹrẹ gbanjo yi ni pe, iwe ti, o nti ọdọ awọn ONIBARA wa wa lati:-

**Ghana, Abijan, Colonou, Lome ati Portnovo**

Ko ni'ye pe ki a tete bẹrẹ GBANJO na.

TETE WA RA TIRẸ LONI

ỌJA GBANJO NA BẸRẸ LATI 28th MAR.–30th APR

Iwe Egbogi Ajebidun 25/— di 22/6d
Iwe Ilana Ifa Iyọrọ ate Etutu ṣiṣẹ 21/- di 18/-
Iwe Afọṣẹ Iṣẹda ẹ Yoruba Psalm Iṣẹgun Ajẹ 4/6d di 3/-
Iwe Ala Nla 7/6d di 5/6d
Iwe Ala ati Iwadi Nkan 2/6 di 2/-
Turari Isẹgun Aje 10/6 di 8/-
Certificate of Appreticeship 7/6d di 5/-
Tailor's Measurement Book 7/6d di 5/6d
Iwe Itan Ala 2/6d di 1/-
Iwe Itumọ Ami Ara 4/6d di 3/-

AKIYESI:— Enikẹni ti o ba ra ninu awọn ọja yi yio gba TURARI IṢẸGUN AJẸ" lọfẹ lati fi dan wa

**Shoyinka**
2/99 Shittu Street
Ibadan

# Imọran Fun Igbesi Aiye Rere

Lati ọwọ:- IYAAFIN AYỌKA TAYỌ

Mo ki gbogbo ẹnyin onkawe irohin Imọlẹ ẹ ku ọjọ mẹta, bakanna ni mo si ki gbogbo ẹnyin obinrin, ẹ ku iṣẹ o ki nto bẹrẹ si dahun awọn ibere nyin mo ni lati tun ran nyin leti pe ki ẹ ma kọ awọn ibere nyin ki o ma han rekete ki ẹ to fi ranṣẹ si mi, ẹniti o ba si mọ pe on ko fẹ ki ndahun ibere on ninu iwe irohin Imọle. ki o fi Stampu tọrọ sinu rẹ ti ngo fi dahun ibere rẹ ranṣẹ si ẹ ku iṣẹ o.

## ẸGBỌN MI FẸ FẸ MI

Mo jẹ ọmọ ọdun mejidinlogun mo si ni awọn ọkunrin ti o fẹ fẹ mi pupọ, ṣugbọn eyiti o wun mi lati fẹ, ti a si jijọ ti se adehun fun ara wa, ni awọn obi mi ni nko gbọdọ fẹ, nitori a tan mọ ara wa, ẹgbọn mi si ni ojẹ, ifẹ ọmọkunrin yi wa lọkan mi pupọ.

Jọwọ, lami loye alanu Obinrin.

SIDIKATU,
EKO.

IDAHUN;- Imoran mi si ọ nipe, o yẹ ki o kọkọ bere ibiti ẹ ti tan, bo ya ni idi Baba ni tabi idi iya, lẹhin na ki o wa mọ bi o ti jina si o to bi o ba jẹ pe o sun mo iya tabi Baba rẹ, ki o ma ṣe fẹ. Sugbọn ti o ba kan jẹ ẹbi nyin lasan ni o le wa ọna ni o fi bẹ awọn obi rẹ ti nwọn o fi jẹki o fẹ.

## BABA MI MBA MI DU IYAWO

IBERE: ? Iyaafin Tayọ orọ rẹ o mo jẹ Ọmọ ogun Ọdun mo si ni iyawo afẹsọna kan ti o jẹ pe o fẹran mi pupọ ti o si jẹ pe igbagbogbo ni o ma nwa mi wa si ile. ti o si ma nba Baba mi Baba mi na mọ Ọmọ-debinrin yi daada, Sugbọn ni aipẹ yi mọ gbọ pe Baba mi lọ ba Ọmọ na, O si sọ fun pe on fẹ fẹ ati igbana ni o si nwa olufẹ mi yi lọ si ile.

Njẹ o yẹ ki fi Iyawo mi yi silẹ fun Baba mi tabi kinni ki nse?

ỌFLANAO RICHARD
ỌYỌ

IDAHUN:- Orlando orirẹ dara ni Baba rẹ fi ba ọ du iyawo. paapa, mo lero pe Iyawo rẹ na, ọkan ni o jẹ ninu awọn Ọmọge ti o dara ni Naijiria.

Ohun ti o yẹ ki o ṣe ni pe ki o kọkọ bere lọwọ Ọmọdebinrin na boya ti o ba jẹ pe iwọ ni o ma fẹ ni tabi Baba rẹ ti o ba sọ pe on si kin fun ọ, nigbana ki o ṣe akiyesi awọn ẹbi baba rẹ si Ọmọ na, ki o si tun sọ fun Iyarẹ nipa Ọmọ na.

## OLUFE MI NFẸ ANTI MI

IDAHUN:- Laipẹ yi ni Ọkunrin fi awọn enia mi ti mọ wa ba mi pe on fẹfẹ mi, mo kọkọ kọ, sugbọn o tun to bi Ọjọ melo kan o tun wa ba mi, mọ si gba lati fẹ lati igbana ni a si ti fẹran ara wa.

Iyaafin Ayọka mi ọwọn, mo ṣẹṣe wa gbọ pe Ọkunrin yi kanna tun nfẹ anti mi, bakanna ni ifẹ ti on pẹlu anti mi yi si tun jinlẹ gẹgẹbi ti emi pẹlu rẹ oju si nti mi nipa Ọmọ yi, nko si mọ ohun ti o yẹ ki nṣe si Ọmọ na.

CELINAN ORẸLAJA
IJẸBU-IMUSHIN

IDANHUN:- Mo kanu rẹ pupọ, Okunri yi le pupọ, o si ewu, mo gba ọ ni imọran lati fi Okunrin na sile lẹsẹkẹsẹ ki o si jẹki Anti rẹ mọ nipa eleyi ki ohun ti o se Okunkun sii, le di imọlẹ.

## E ma ka Irohin Imọlẹ lojojumr


AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid–Ul–Kabir Dance**
AT
**FORSTER CENTENARY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th Apri 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn
*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDIN G
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest heats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/– Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16. Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ's Office Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute–Mẹtta.



## Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igbor joko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Egboo ulu ko ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ingi "Ikọ" si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹ iti oti bere fun egbogi wọnyi:

**"Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi 'Linituss'**

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ik ki Igbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki nia ma ha ọna-ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsana t oru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri.

O daju nibẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yọn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Bere egbogi ajẹbina Richelet yini ṣọbu awọn

Waterloo Medicine Store
8, Plamchurch Street,Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja ita Faji)



# Kere o!

Fun ani fun gbogbo ẹnyin oniṣowo, Iwe Irohin Imọlẹ yio ṣe ipolowo awọn ọja nyin fun nyin ni ọsẹ kan gbako ki ọdun Ileya o to de ati lẹhin ọdun ki awọn onibara nyin le ba nyin ra ọja ti ọdun Ileya ti mbọ yi.

Awọn Aṣoju wa yio ma a lọ kakiri lati bere fun awọn ti o ba fẹ lati polowo ọja wọn ninu Iwe Irohin wa.

Omo pọọku ni a ngba, dan wa wo lẹkan ki o sri bi ajo rẹ yio ti ta to,Ijafara lewu o.

# IROHIN IMỌLE

, Ḷ IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 579 TUESDAY, APRIL 14, 1964 (2D)


## Edokpolor Yọ Otobo Kuro Ninu Ẹgbẹ M. D. F.

BINNI:— Olori ẹgbẹ M, D. F (Mid West Democratic Front) ti awọn ẹgbẹ na na yọ kuro ninu ẹgbẹ na laipẹyi Ojiṣẹ Ọlọrun John Edokpolor ti paṣẹ lati yọ awọn meji ninu awọn olori ẹgbẹ na awọn meji na ni Ọgbẹni James Otobo ti o je igbakeji alaga ẹgbẹ na ati Oloye C. I. Akere ti o si tun jẹ ọkan ninu akọwe ẹgbẹ na.

Aṣe yiyọ awọn olori wọnyi jade ninu ipade kan ti awọn ọmọ ẹgbẹ a ṣe ni ọjọ keje oṣu yi.

Ojiṣẹ Ọlọrun Edokpolor sọ ninu ọrọ rẹ pe, yiyọ awọn olori wọnyi ki yio ni ayipada titi nwọn yio fi ṣe alaye gẹgẹbi nwọn ṣe na owo ẹgbẹ na, eyiti nwọn gbọdọ ṣe iṣiro rẹ.

Awọn meta ninu awọn Olori ẹgbẹ na Oloye Enahoro Baba Anthony, Enahoro, Oloye A. Asueh ati Oloye A. Begho ni awọn ẹgbẹ na ti yan gẹgẹbi oluṣiro owo awọn ẹgbẹ na.

Ninu ọsẹ tokọja ninu ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe ni ilu Agbor ni nwọn ti yan Ọgbẹni James Otobo gegebi Olori ẹgbẹ na lati rọpo Ojiṣẹ Ol run Edokpolor ti awọn ẹgbẹ na yọ kuro ninu ẹgbẹ na ni ọsẹ to kọja.

# AWỌN IJẸSHA HA NWA OLOYE AKINTỌLA BI?

ILESHA:- Gbogbo awọn ara ilu bẹrẹsi sare kakiri gbogbo arin ilu ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanla osu yi nigbati nwọn gbọ irohin kan wipe oloye S. L. Akintọla, olori ẹgbẹ Dẹmọ (N.N.D.P.) ati oloye Fani-Kayọde ti iṣe igbakeji rẹ pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ mbọ wa si Ilesha pẹlu "Ọkẹ-aimọye' awọn ọlọpa ninu mọto.

Irohin fi ye wa wipe, awọn ara ilu na ti gbọ wipe Oloye Akintọla pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ nlọ si Ekiti ati Ondo.

Ṣugbọn ko pẹ lẹhin na ni nwọn ri mọto kan ti o sare kọja bi kannakanna larin ilu ti nwọn si kọ orukọ ẹgbẹ Dẹmọ si ara mọto na.

Lẹsẹkẹsẹ ni irohin gba gbogbo ilu wipe Oloye Akintọla mbọ, ọna Ilesha ni o ngba lọ si Oshogbo, Lojukanna ni awọn enia ba nsare wọ ile ti, nwọn si njo wipe, "ohun ti yio ba gba ni ao fun un loni, ọlọpa ko tun ni mu ẹnikan ninu ilu yi loni, iwoyi ijẹjọ niyi ti ọlọpa nko enia bi a nwa igongo lori akitan.



Oloye S. L. Akintọla

Ko pẹ pupọ bi awọn enia na ti duro si Ode ni nwọn ri moto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun kan ti o sare kọja ni dede agogo mọkanla, ti awọn enia kan si sọ wipe mọto Oloye Akintọla ni awọn miran sọ wipe awọn ri Oloye Akintọla ati Fani-Kayọde ninu Ọkan ninu awọn mọto mejeji na.

Ko pẹ pupọ lẹhin eyi ni nwọn ri awọn moto Ọlọpa ti o kun ini moto kan ti on na tun kọja lẹhin na, ṣugbọn ko si eyiti o duro inu awọn moto na ni Ilesha.

Irohin fi ye wa pe nigbati awọn mọto na kọja niwaju Ile-ẹko Ilesha, nṣe ni awọn Ọmọ Ile-ẹkọ na ho le wọn lori gee!

Lẹsekese ti irohin kan awọn Ọlọpa ni Teṣan Ilesha ti nwọn si ri bi awọn enia won ti ṣe ngmura "Ogun" Ọbẹ, Ada, Akifọ-igo ati awọn Ohun Ọṣe miran, ni awọn Ọlọpa ba duro kakiri gbogbo awọn Origun larin ilu.

Ṣugbọn a gbọ wipe, iṣẹlẹ kankan ko ṣelẹ si ẹnikan, ni Ọjọ na.

## Agbẹjọro Awolọwọ Kọlu Akintọla


LATI OJU EWE KINI


Ọgbẹni Durand ni "adajọ ṣi ara rẹ lọna nigbati o so wipe on ko le gba ẹjọ ti Oloye Awolọwọ ro gbọ.

O wa pe akiyesi awọn adajọ si ọrọ rẹ, pe, Nigbati awọn Ọlọpa lọ si ile Oloye Awolọwọ, ni igba kini, nwọn ko ri nkankan ninu ile rẹ, ṣugbọn nigbati nwọn lọ nigbati Ijọba ti fi ofin pajawiri gbe Oloye Awolọwọ ni nwọn wa sọ pe awọn ri ohun ọṣẹ ninu ile rẹ.

Ati pe, ninu ile kọ ni nwọn ti ri awọn ohun ọṣẹ na ni arin ọgba nibikan ni ẹhinkule ni awọn ti ri awọn ọta-ibọn na, o wa bere pe, "Kini ṣe ti nwọn ko ri nkankan nigbati awọn Ọlọpa kọkọ lọ si Ile Awolọwọ ni Ikẹnnẹ ?"

O tun ṣe alaye pe, nitori idi eyi, edeaiyede da silẹ larin awọn Ọlọpa ti o lọ si ile Oloye na ni ọjọ na lohun, eyi fihan wipe, awọn enia na nṣiye meji si ohun ti o ṣẹlẹ.

O ni Ọgbẹni John Lynn, Ọga awọn Ọlọpa paapa sọ niwaju adajọ pe, awọn kan le ti lọ gbẹ ilẹ, ki nwọn si ri ohun ọṣẹ na si Ile Oloye Awolọwọ o wa rọ adajọ lati gba ọrọ na yẹwo.

### IJẸRI EKE

Gbogbo ile lo fi Ọwọ le igbọn nigbati ar ofin na nsọ fun Ile ẹjọ pe, ki adajọ o maṣe gba Ọrọ ti Olear sọ gbọ.

O ni Oleari sọ wipe ni Ghana ti on l , ni on ti gbọ ninu ẹrọ Redio pe, Ijọba ti fi Ofin Pajawiri gbe Awolọwọ kuro ni Ile rẹ, ninu Oṣu kẹfa Ọdun yi.



Ọgbẹni Ọlawọyin

Ọgbẹni Durand ni, ni Ọjọ kọkandinlọgbọn Oṣu karun Ọdun ti 1962 ni Ijọba fi Ofin pajawiri gbe Oloye Awolọwọ, Oleari si wa ni Naijiria nigbana, Ṣugbọn nigbati o de Ghana ni Oṣu kẹfa ni o wa to gbọ ninu ẹrọ Redio ni Ghana pe Ijọba fi Ofin pajawiri gbe Awolọwọ

O wa rọ adajọ pe ki nwọn fi igi si idi ẹjọ ti Oleari ro niwaju adajọ, o ni on nbọ wa fi abọ ba ẹjọ na nigbati Ọrọ ba debẹ.

Ọgbẹni Durand wa ṣe alaye pe, ni ipari Ọrọ rẹ, Ọgbẹni Oleari papa sọ fun Ile ẹjọ pe, On ko ni ibalẹ Ọkan lati igbati On ti rojọ fun awọn Ọlọpa tan.

Nibiyi ni o ba ọrọ rẹ de ti agogo kan abọ ọsan fi lu ti Ile ẹjọ na si mu ipade ijoko wọn wa si opin.

Nwọn o tun ma a ba ijoko wọn lọ ni owurọ yi.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street P O Box 1495 Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga Lagos (13/4/64)